Musulumi ti wọn ba bi i leere ninu saare: O maa jẹrii pe ko si ẹnikan ti ijọsin tọ si afi Allahu ati pe dajudaju Muhammad ojisẹ Ọlọhun ni

Lati ọdọ Al-Baraa ọmọ 'Azib- ki Ọlọhun yọnu si i- dajudaju ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: "Musulumi ti wọn ba bi i leere ninu saare: O maa jẹrii pe ko si ẹnikan ti ijọsin tọ si afi Allahu ati pe dajudaju Muhammad ojisẹ Ọlọhun ni", ìyẹn ni ọrọ rẹ pé: (Allāhu yóò máa fi àwọn t’ó gbàgbọ́ ní òdodo rinlẹ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ t’ó rinlẹ̀ nínú ìṣẹ̀mí ayé àti ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn (Ibrahim, Ayah 27).

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Wọn maa bi olugbagbọ leere ninu saare, awọn mọlaika meji ti a fi ṣe amojuto ìyẹn maa beere lọwọ rẹ nipa ìyẹn, awọn mejeeji ni Munkar ati Nakeer, gẹgẹ bi orúkọ awọn mejeeji ṣe wa ninu ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn hadiisi, O maa jẹrii pe ko si ẹnikan ti ijọsin tọ si afi Allahu ati pe dajudaju Muhammad ojisẹ Ọlọhun ni, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe eleyii ni ọrọ ti o fi ẹsẹ rinlẹ ti Ọlọhun sọ nipa rẹ pé: (Allāhu yóò máa fi àwọn t’ó gbàgbọ́ ní òdodo rinlẹ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ t’ó rinlẹ̀ nínú ìṣẹ̀mí ayé àti ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn (Ibrahim, Ayah 27).

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/4206